**OWE**

OKU eşinşin mu ororo ikunra olorun didun bajẹ ki o ma fi run oorun didun mọ. Bẹni were diẹ wuwo ju ọgbọn ati ọla lọ.

**Irohin Yoruba**

804 NOVEMBER 2 — NOVEMBER 8, 1960 Kobo Meji (2D.)



Dara fun Ẹjẹ Ọmọde, Agba ati Aboyun

O wa fun tita kakiri De-egbogi

# IBỌN NGYIN FUNRA RẸ NIBI ERE AWỌN ỌDẸ

## ARA [LẸBA ẸDẸ]

**Agbayanu ni ere ariya ti awọn Ogboju-ọdẹ ologun Oke Ọtin gbarajọ wa şe ni ilu Ara lẹba Ẹdẹ f u n aşeyẹ ajọyọ ominira ti Apapọ Ijọba Naijiria gba ni ọjọ Abamẹta ti işe ọjọ kini oşu kẹwa ọdun yi.**



Awọn ogboju-ọdẹ na ni nwọn wa ninu aworan ẹgbẹ ọtun yi, orukọ wọn si ni Raji Ogundiran lati Eripa lẹba Ikirun; Agbala Odo lati Ọtan Aiyegbaju; Oketọla Olukọtun Ọdẹ Ire lati ilu Irre; Ogunyẹmi Oyewo Inisha-Ile, Salako lati Iragbiji; Salami Ikirun lati ilu Ikirun; ati J. O. Daradedi ti işe olori ọdẹ.

Nigbati awọn ọdẹ na pagbo ere wọn tan, ti ẹsẹ si pe bamu-bamu sibẹ tan ni awọn ọdẹ yi ba bẹrẹsi lu ilu wọn, nwọn npogun, nwọn si nkijala ni ọkọọkan. Nwọn pa orişirişi idan, gbogbo awọn ero iworan si bẹrẹsi pariwo, nwọn nyọmbo wọn, nwọn si nkigbe pe "Ogun ye e!

Ohun ti o jẹ iyalẹnu ninu ere wọn na ni pe bi awọn ọdẹ yi ti nkijala pẹlu ohun aro ni awọn ibọn wọn ti wọn gbe ti bẹrẹsi yin funra wọn laijẹ wipe ẹnikan fi ọwọ kan wọn, tabi sunmọ wọn.

Eyi tun mu gbogbo awọn ero iworan kigbe pe: "Ogun yee!"

# Ọbaro Kabba gba ọpa oye



... yi ni ti gbati Ọba Alaiyeluwa Daniel Aka ti gba ọpa oye rẹ gẹgẹbi Ọbaro Kabba

IROHIN ko to afojuba ni aseyẹ ifinijoye ti awọn Afọbajẹ ati gbogbo ilu Kabba şe fun Oloye Daniel Aka ni agogo mẹsan owurọ ọjọ Işẹgun ti işe ọjọ kẹtadinlogbọn oşu kẹsan ọdun yi. Ni ọjọ ọna ni o gba ọpa oye rẹ gẹgẹbi Ọbaro Kabba.

Ẹsẹ gbogbo awọn enia ja-nkan ja-nkan bi Ọba, Ijoye ati awọn gbajumọ yika gbogbo iileto ilu Kabba ni o pe-şoşo si ibi aşeyẹ na, Awọn ọlọpa Ibilẹ ati awọn ọmọ ile iwe to ilo ẹyẹ, awọn obirin Ile EKỌ (Women Training Centre) si kọ orin Ibilẹ Naijiria titun ni ibi ẹyẹ ifinijoye na.

Ni owurọ ọjọ kanna gan an ni Ọgbẹni J. E. Baker, Ajẹlẹ-Agba Ijọba Ipinlẹ Ariwa wa si Kabba lati Lọkọja, o si fun Ọba titun na ni ọpa oye.

Ninu ọrọ rẹ, Ajẹlẹ-Agba so fun Ọbaro titun na pe, ki o fẹran awọn enia rẹ gẹgẹbi ara rẹ, ki o ma si şe korira ẹnikẹni. O ni 'tori aiko tete mọ eniti yio joye na ni ko ti jẹki nwọn jẹ ẹ lati ọdun mẹta sẹhin, o si rọ gbogbo ara ilu pe ki nwọn fi ọwọ sowọ pẹlu ọba na fun idagbasoke ilu wọn. Ọba titun na si şe ileri nigbati o nfesi si ọrọ Ajẹlẹ Agba na. O ni on dupẹ lọwọ gbogbo ara ilẹ Owe fun oye ti nwọn fi da on lọla na, on yio si fi gbogbo ọjọ aiye on josin fun wọn. O si dupẹ lọwọ Ajẹlẹ-Agba na ati awọn Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa fun aayan wọn lati fi on jẹ oye na. O şe adura pe ki Ọlọrun jẹki ilu Kabba ni ilọsiwaju.

O si şe ileri lati pa aşẹ Ijọba Ipinlẹ Ariwa mọ.

## Akpan ti ina bọ Şọọşi

ABAK

LENULỌLỌYI ni awọn ọlọpa mu ẹsun ọkunrin kan ti nwọn npe ni Idana Udoh Akpan, ẹni ọdun mẹtadinlogbọn wa siwaju Adajọ pe o ti ina bọ Şọọşi Apọstọli ni ilu Abak ni Ipinlẹ Ila-Orun.

Ẹjọ ti awọn ọlọpa ro mọ ọ ni pe, tẹlẹtẹlẹ ni Akpan ti sọ ohun ti on yio şe ni Şọọşi Apọstọli na; nwọn si tun sọ pe nigbati ina na şẹlẹ, awọn Ilọ Apọstọli ni nwọn ri i ni agbegbe şọọşi na pẹlu işana lọwọ.

Nigbati Adajọ ri pe o jẹbi ẹsun na, o ju si ẹwọn ọdun meji gbako.

# Ẹgbẹ 'Co-operative' ṣe ipade ajọdun kini

## Oloye Obiṣẹsan sọrọ iwuri

EGBE ile-iṣẹ owo ajumọṣepọ (Nigerian Co-operative Federation Ltd.) ṣe ipade ajọdun kinni ni ọjọ Ọjọru ti iṣe ọjọ kokandilogun oṣu yi ninu gbọngan apejọ (British Council Hall) Yaba.

Ipade na bẹrẹ ni agogo mẹwa owurọ. Oloye Akinpẹlu Obiṣẹsan Alaga Igbimọ Ile-iṣẹ owo ajumọṣepọ (Nigerian Co-operative Federation Ltd.) ni o si ṣe alaga ipade na. Ninu ọrọ rẹ, Oloye Obiṣẹsan ni on dupẹ pupọ lọwọ awọn ọmọ Ẹgbẹ ti o fi ipo alaga yi da on lọla, on si tun dupẹ nipa ọrọ apọnle ti ọpọlọpọ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ nipa on.

O ni, nitotọ on jẹ igi lẹhin ọgba fun awọn ẹgbẹ ile-iṣẹ owo ajumọṣepọ ṣugbọn bẹ ẹ na si ni on tun jẹ iranṣẹ ati ọmọ ọdọ fun wọn pẹlu. O si tun gba wọn ni iyanju lati tẹle oruko ẹgbẹ wọn "Cooperative" eyiti itumọ rẹ jẹ irẹpọ, ti yio si mu enia ilẹ Naijiria ni ilọsiwaju, paapa lasiko yi.

Bakanna ni Oloye Obiṣẹsan tun dupẹ lọwọ ọmọ ẹgbẹ na ti nwọn wa lati Iha Iwọ-Orun, Ila orun ati Gusu si ipade ajọdun kinni na.

Ọgbẹni D. A. Ebe ti o sọrọ tẹle e dupẹ lọwọ Oloye Akinpẹlu Obiṣẹsan alaga won loruko ẹgbẹ na.

Diẹ ninu awọn enia ja-nkan ja-nkan ti o wa si ipade na ni awọn Ọgbẹni Shoyẹmi Ṣonaike, O. A. Adeṣida, F. Adeyẹmi, O. A. Adebiyi ati Ọmọ-ọba G. Adedamọla.

## Ọdẹṣọla komọjade

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ ketalelogun oṣu kẹsan ọdun yi ni Ọgbẹni Isaac Ọdẹṣọla (Baba-ibeji) ṣe ikomọ ọmọbirin ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ Abigael lọrẹ. Nwọn si sọ orukọ ọmọ na ni Makaret Iyabode.

Ọpọlọpọ awọn enia pataki-pataki ni o wa si ibi ayẹyẹ ikomọjade na. Irohin ko si to amojuba ni aṣeyẹ ọjọ na, bi onilu ti nfi kọkọrọ ilu rẹ dara ni awọn alabaṣeyẹ paapa njo bi kokoro. Bi awọn alabaṣeyẹ na si ti pọ to ni baba ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ wọn lọrun to.

Diẹ ti aye wa fun lati darukọ ninu awọn alabaṣeyẹ ikomọ na ni awọn Ọgbẹni B. Amọdẹ, Gbada Ayinla, Asani, Ọmọnijẹ L. Oluwalowi, Folọrunṣọ Sunday ati awọn Iyaafin Felicia Folọrunṣọ, Muniratu Asabi, Muniratu Abakẹ, Sifawu Amokẹ, Rabiatu Arinpe, Lydia ati Sariyu Alake.

Ki Oluwa fi ire kari awọn alabaṣeyẹ ki O si ṣe ọmọ na ni olori ire o.

## Ọdẹbiyi yọ ayọ ominira

IDOFI AIYETORO-EGBADO

OLỌLA J. A. O. Ọdẹbiyi ṣe ajọyọ ominira ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹdogun oṣu kẹwa ọdun yi. Ẹṣọ awọn Ọba, Olọla Oloye, gbajumọ ati mẹkunnu, ni o pe ṣọṣọ si ibi aṣeyẹ na. Olọla J. A. O. Ọdẹbiyi si fi orişirişi onjẹ ati ọti tẹ gbogbo wọn lọrun.

Awọn Ọgbẹni Awalyewaṣọla Adisa, S. A. Akanimọle, E. O. Ọkẹ, Kasali Omifunmikẹ ati S. Akintọla wa ninu awọn enia pataki ti o ṣe ajọyọ alarinrin na.

## Alongẹ di Alakoso iṣẹ Mandilas l'Eko

ENITI o wa ninu aworan oke yi ni Ọgbẹni Joshua A. E. Alongẹ ti awọn Igbimọ Alakoso Ile-iṣẹ Mandilas ati Karaberis l'Eko yan si ipo aye Alakoso-iṣẹ wọn laipẹ yi. Lati igbati nwọn ti da iṣẹ na silẹ ninu ọdun 1944 ni Ọgbẹni Alongẹ ti bẹrẹ iṣẹ labẹ wọn, ọmọ ilu Ibini si ni.

Nigbati Ọgbẹni Alongẹ wa ni ọmọ ile-iwe ni ọdun pupọ diẹ sẹhin ni o se alabapade pẹlu Ọgbẹni John Mandilas ti iṣe Olotu ati Alakoso Iṣẹ Mandilas ati Karaberis.

Ṣugbọn nitoripe o jẹ ọmọ ti o fẹran ẹkọ pupọ, ti awọn obi rẹ ko si ni agbara to lati ran an lọ, ni Ọgbẹni Mandilas ba nsanwo ẹkọ rẹ. Nigbati o jade ile-iwe, o siṣẹ ni ile-iṣẹ mejeji ọtọọtọ, lẹhin ọdun diẹ, o si bẹrẹ iṣẹ labẹ ọga rẹ atijọ, Ọgbẹni Mandilas.

Ni akọkọ bẹrẹ iṣẹ, nwọn gba a gẹgẹbi ọmọ-iranṣẹ (messenger) nigbati o si farahan gẹgẹbi ọmọwe ati oṣiṣẹ ti o jafafa, ni nwọn ba tun sọ ọ di akọwe, nigbati o si tun nṣiṣẹ pẹlu ododo ati gbogbo agbara rẹ, ni nwọn ba fi yan an si ipo Alakoso-iṣẹ.



ỌGBẸNI J. E. A. ALONGẸ

* * *

Awọn ọmọ Naijiria mẹrinla ni o wa ni ipo ọga, awọn kan wa ni ipo alamojuto-iṣẹ, onişiro-owo ati onişẹ-ẹrọ, awọn mejila miran si ṣetan lati bọ si ipo-ọga larin ọdun kan tabi meji si i.

## AKIYESI

**Ẹnikẹni ti o ba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti o si wa laaye, ki o kọ ọ sọwọ, tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu itan iṣẹdalẹ Yoruba. A o si tẹ ẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ ku iṣẹ o.**

OLOTU

Nję o ti ri AJAPA ALAWỌ-ALIGA RI BI?



O ṣẹṣẹ de si ile-itaja adugbo rẹ ni!

Ajapa Alawọ-Aliga ni ẹni ayanfẹ ti o le ri lara gbogbo awọn Panu-onjẹ ti ile-Iṣẹ Alumaco titun ṣe ni Apapa. On ni o joko lori awọn ikoko-irin-afuyẹ ati awọn panu ti o ndan yanranyanran ti o si nwoye pẹlu ifaiyabalẹ si ara rẹ nibẹ yi. O le jẹwipe bi o ti wi ni o ri—awọn ikoko ati panu rẹ ni o darajulọ ti o le ra—wọn lagbara to bẹ ọ gẹ ẹ, nwọn ko le faya tabi ki nwọn dipẹta. Nwọn tun dinwo pẹlu nitoripe nwọn ni alopẹ pupọ ju iru awọn awo-onjẹ miran lọ. Ma a fi oju wa Ajapa Alawọ-Aliga ni Ile-Itaja adugbo rẹ.

AWỌN AJAPA ALAWỌ-ALIGA jẹ ayanfẹ pataki ninu gbogbo awọn Ile-idana igba isisiyi.

ẸNYIN ONIṢOWO
Bi ẹ ko ba ti i ra awọn Ajapa Alawọ-Aliga sinu ṣọbu nyin—ẹ tete wa ri wa kiakia.

Awọn ti o nṣe nikan ni

ALUMACO, P.O. Box 60, Apapa, Lagos,
Telephone: — 55715

# Tani Musulumi ododo?

## Lati ọwọ Mohammed Ameen

NI oruko Allah, Olore-ọfẹ Alaanu julọ.

"Ki iṣe iwa ẹtọ, iwa ododo, pe ki ẹ ma a wa yi oju nyin si iyọ-orun owurọ, tabi Iwọ-orun alẹ nikan. Şugbọn oniwa ododo ni ẹni na ti o gba ti Allah gbọ pẹlu Ọjọ Ajinde tira ti Ọlọrun awọn alasọtẹlẹ ati ẹnití o ngna ohun ọrọ rẹ nitori ifẹ ti Ọlọrun nikan si awọn ẹbi, awọn ọmọ orukan ti obi wọn ti jalaisi, awọn alaini, awọn arin irin ajo, awọn ti nwọn ntọrọ ẹbun lẹhinna ti nwọn tun wa nfun awọn ẹru ni ominira kuro ninu igbekun, ti nwọn si nkirun dede, ti wọn nyan sakat'... awọn ti nwọn ngmaa mu ileri wọn ṣe nigbati nwọn ba ṣe ileri tabi adehun kan, awọn onisuru ninu ipọnju, ijiya ida-loro ati ni aseko ẹru-jẹjẹ? ipalya ogun. Awọn wọnyi ni awọn olododo enia, ti nwọn mbẹru Oluwa wọn pẹlu itọju iṣẹ wọn gẹgẹbi o ti tọ, to si yẹ "—Alkurani Mimọ 2: 177.

Nkan pataki ti Islam nfi kọ wa ninu ọrọ oke yi nipe ki iṣe ki a kan ma a yi oju wa si iyọ tabi Iwọ-Orun nikan ni ẹsin Islam. Şugbọn o jẹ ẹsin Islam ododo ni ki awa enia gba Allah gbọ pe Ọba kanṣoṣo ni iṣe, lalgbagbe pe bi o ti wulẹ ki o pẹ to, ijọ kan yio de ti ẹda ni lati jẹ abọ iṣẹ ọwọ ati iwa rẹ fun Ọba ti o da a fun igba iyi tabi fun ijiya,

### ITỌJU ẸBI

Ohun ti ọrọ Alkurani ẹsin ọrọ mi nsọ nipe ẹnikan koi ti di ẹni ododo ayañ igbati o ba nñ ifẹ inu ngna awọn ohun ọrọ rẹ si oju ọna Ọlọrun, Islam laljẹpe ẹnikẹni mu oluwarẹ nipa. Ọrọ na ko duro ni ibiyi. O tun nf'iyẹ wa pe gbigba awọn nkan wọnyi gbọ koi tun ti sọ ni di ẹni ododo niwaju Oluwa bi ko ba di igbati a ba bẹrẹ si ṣe itọju okun ibi ati ti awọn ibatan,

Bẹna ni a ko gbọdọ fi iṣe itọju awọn ọmọ orukan sẹhin ninu iṣẹ ati iwa ẹni nitori a ti di ẹni ododo niwaju Ọlọrun. Ki iṣe awọn orukan nikan, itọju awọn alaini paapa ṣe pataki pupọ bi ti awọn arin irinajo ati itọrẹ anu fun awọn onibara atọrọjẹ, ati lati ma ripe awọn ẹru ti o wa ninu igbekun na ri ominira gba ti o ma sọ awọn di ọmọluabi.

Lẹhin ti a ba nṣe gbogbo awọn eto wọnyi tan ni a ni lati wa bẹrẹ si ri pe



MOHAMMED AMEEN

a ko ye ki irun wakati mararun ni aseko ni ojojumọ, bẹni a ko si gbọdọ kuna, lati ma san owo ti nwọn fi ma ntọju awọn alaini l'ọdọdun lori awọn ohun ọrọ ti a kojọ fun odidi ọdun kan gbako ti nwọn npe ni 'SAKAT'.

### IKILỌ PATAKI

Ikilọ pataki ti o tun wa ninu ọrọ Alkurani Mimọ yi, ni bi o ti ṣe pataki to lati le ma ro ọran wo dada ki a to bẹrẹ si jẹjẹ fun enia, atipe bi a ba si ti ṣe ileri na tan o ti di nkan aigbọdọ fun wa lati ri pe a ngmu awọn ileri ẹni na leto. Bi o ba si jẹpe nigba inira ni a ba ṣe ileri, bi idẹra ba de, a ko gbọdọ sọ pe ẹsẹ wa ti to lẹ tan nitorina ki a wa gbagbe aseko inira.

Idi niyi ti Alkurani Mimọ 61: 2,3 fi sọ bayi pe.

"Ẹnyin Onigbagbọ ododo nitori kini ẹ fi ma a nsọ ohun ti ẹ mọ pe ẹ ko ni le ṣe tabi ki ẹ ma a sọ ohun ti ẹ ko ni muṣẹ jade lẹnu? "O jẹ ohun ti Ọlọrun Ọba Allah korira lọpọlọpọ, pe ki ẹ ma a sọ ohun ti ẹ ko ni le ṣe jade lẹnu.

Nitorina, ẹnyin onigbagbọ ododo, nigbakugba ti ẹ ba ma ṣe ileri. O di iwọ aigbọdọ si nyin lọrun lati ma a mu ileri nyin ṣẹ fun enikẹni t'o le ṣe, bi o ti wulẹ, ki ọwọ egba pọ lomi to. Eleyi ni nwọn npe ni ọmọluabi.

Ni kukuru, bi ẹ ba fẹ jẹ Musulumi ododo, ẹ ni lati gba Ọlọrun, Ọba Allah, ọjọ ajinde, awọn malaika, tira Ọlọrun. ati awọn Anabi gbọ pẹlu inawo si oju ọna Ọlọrun ni oniruru ọna.

Assalaimu-alaikun!







## Akede Ọna Igbala

# Iwọ ha ti di ominira bi?

OHUN iyanu ni o jẹ fun mi nigbati ọkunrin kan ti o joko pẹlu mi ni ọdan ti o mbi ekeji rẹ lere wipe, "Iwọ ha ti di ominira bi?. Ni alẹ ọjọ Abamẹta ti a gba ominira ni ori koriko ni ọdan nibiti ainiye awọn enia ti nworan, ni mo joko pẹlu awọn ọkunrin meji ti gbogbo wa jijo woran awọn ti nṣere nibẹ.

Lẹhin igbati nwọn ti fa asia Gẹẹsi wa ilẹ ti asia ominira Nigeria si wa loke ti gbogbo awọn enia nṣapẹ fun ayọ ti ominira ti o wọle de ti nwọn npariwo lọtun losi.

Nigbana ni ọkunrin ti mo joko ti yi mbere lọwọ ekeji rẹ pe: "A ti gba ominira ti orilẹ-ede wa nisisiyi, ṣugbọn o ku ominira ti ẹnikọọkan ti a nilati gba." Idahun ti ẹnikeji si fun un ni pe ko tun si ominira ti o ku fun on mọ lati gba nitori on ti di ominira ara on lati igbati on ti kuro lọdọ awọn obi on ti on si ti nda iṣẹ ṣe lati fi wa onjẹ ojọ on kakiri.

IBERE EKEJI

Ṣugbọn ọrẹ rẹ na tun bi i ni ibere keji bayi pe, "nje iwọ ha ti di ominira ninu Jesu Kristi bi?" O si dahun pe on ko mọ pe ominira kan tun wa ninu Jesu Kristi, nitoripe on ko gbọ ohun ti o jọ bẹ ri yatọ si ominira orilẹ-ede.

Lẹhinna ni ẹnikeji rẹ ṣe alaye fun un pe ominira kan wa t'a o ni bi awa ba fi ọkan wa fun Jesu ni Oluwa ati Olugbala wa. Nitori Jesu ni ominira kan ti o ju ominira ti aiye lọ bi awa ba gbẹkẹle E ti a si mọ Ọ ni Oluwa, yio si sọ wa di ominira totọ ninu Rẹ eyi ti iṣe ti Ẹmi ti o si tobi ju gbogbo ominira ti aiye lọ.

Okunrin na sunmọ ọrẹ rẹ lati mọ bi on ti ṣe le ni ominira ninu ẹmi, nipasẹ Jesu Kristi, o si bẹ ọrẹ rẹ wipe ki o la ye on nitori on ti ro wipe on ti di ominira loju ara on nigbati on ko tun si labẹ itọsọna awọn obi on mọ. O daju wipe okunrin na mọ nipa ominira ti ẹmi ni ọjọ na o si gba ominira ti ara pẹlu.

Ọpọ awọn enia ni nwọn ti nro wipe awọn ti di ominira nitoripe awọn ko sin ẹnikan mọ awọn nsin ara wọ ni, awọn si mbọ ara wọn ti nwọn ko si mọ pe ominira ti a nwi yi yatọ si eyiti nwọn nro ninu ọkan ara wọn. Nigbati orilẹ-ede Nigeria ni apapọ ti gba ominira, ọpọ awọn enia ni nwọn yio ma a fi han awọn enia miran wipe awọn na wa ninu ominira nisisiyi, awọn si wa ninu yọtọmi, ko si ohun ti o ku mọ j— pe ki awọn ma a jẹ ki awọn si ma a gbadun lọ.

IBERU OLUWA

Njẹ iwọ ọrẹ mi ti nka iwe yi, boya iwọ na ti ro wipe o ti di ominira nigbati orilẹ-ede Naijiria ti di ominira tabi nitori iwọ na ti kuro labẹ itọsọna awọn obi ti o si wa fun ara rẹ. E maṣe ni ero yi ninu nyin nitoripe ẹnikẹni ti ko ba ni bẹru Ọlọrun ninu iṣẹ ọwọ wọn ti nwọn ko si fi imọ Ọlọrun siwaju ohun gbogbo ti nwọn nṣe, bi nwọn tilẹ ti gba ominira nipa ti ara, nwọn si jẹ ẹru ẹṣẹ sibẹ.

Gẹgẹ bi a ti nṣe ajọyọ nla fun ominira ilẹ wa ti a si nfi gbogbo awọn iṣẹ nla ribiribi ti a ṣe han, ti inu gbogbo wa si ndun lati gba ominira na pẹlu ayọ ati ifẹ. Bẹ gẹgẹ ni yio ti ri fun ẹlẹṣẹ kan ti o ba ronupiwada kuro ninu ẹṣẹ rẹ ti o si gba Jesu gbọ sinu ọkan rẹ.

Iru iyi nla yi ni angẹli yio ṣe fun iru ẹnibẹ ni Ọrun ti awọn enia mimọ yio si ma a kọrin ayọ lati fi ki ẹniti a fa pada ninu ẹjẹ ọdọ agutan Ọlọrun Jesu Kristi na kabọ. "Mo wi fun nyin gẹgẹ bẹli ayọ yio wa li ọrun lori ẹlẹṣẹ kan ti o ronupiwada," (Luku 15: 7). Bi iwọ ti nka iwe yi ba gba Jesu gbọ loni lati di ominira nipati ẹru rẹ ayọ nla mbẹ fun ọ ni ọrun ju eyi ti a ṣe ni ọjọ ominira yi lọ. "Tọ ọ wo ki o si ri pe rere ni Oluwa."

ỌRUN APADI

Njẹ kini nda ọ duro loni lati wa ominira titi aiye, ominira ainipẹkun eyi ti iwọ yio ni titi pẹlu ẹmi itẹlọrun lai si iberu awọn ọta? Iwọ maṣe fi falẹ rara loni lati wa ominira nitori ẹnikẹni ti o ba wa ninu ide Eṣu ti o si nṣe iranṣẹ fun un yio jiya ninu ọrun apadi titi aiye. Ohun ohun ti Ọlọrun nwi fun ọ loni pe, "Nitorina bi Ọmọ ba sọ nyin di ominira, ẹ o di ominira nitotọ" (Johannu 8: 36).

Jesu Kristi nikan ni o le sọ ọ di ominira totọ kuro loko ẹru Eṣu. "Nitorina ẹ duro ṣinṣin ninu ominira na eyi ti Kristi fi sọ wa di ominira, ki ẹ ma si ṣe tun fi ọrun bọ ajaga ẹru mọ" (Galatia 5: 1).

Jesu yio sọ ẹniti o ba wa si ọdọ rẹ di ominira, O si nsọ fun wa pe ki a maṣe lọ si ọdọ Eṣu mọ ki a bọ ajaga Eṣu silẹ. Wa gba ominira rẹ loni lọdọ Kristi, ki o si gba otitọ Rẹ gbọ. "E o si mọ otitọ, otitọ yio si sọ nyin di ominira" (Johannu 8: 32).

## AKIYESI PATAKI

**A fẹ ki gbogbo ẹnyin aṣoju wa ati onkawe kakiri agbaiye ma a fi irohin pataki ti o ba ṣẹlẹ ni ilu ti ẹ ngbe tabi itan aladun sọwọ si wa. Ki ẹ si gbidanwo lati ma a fi fọto irohin na sọwọ si wa ki ẹnikẹni le ri idaniloju ohun ti o ṣẹlẹ na, ati aworan na ati irohin na lọfẹ ni a o tẹ ẹ jade fun nyin. Ajunmọṣe wa ko ni bajẹ o. OLOTU**

## Elegbede ko ibeji ọmọ rẹ jade




NI ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu ti o kọja yi ni Ọgbẹni Elegbede ṣe ikomọ ibeji ti Ọlọrun fi ta on ati aya rẹ lọrẹ. Nwọ nṣe isin ikomọ na ni ṣọọṣi ni owurọ ọjọ na. Alufa Ọdọ ni o si ṣe isin isami.

Ninu aworan oke yi ẹ o ri awọn obinrin meji ti nwọn gbe awọn ẹdun na dani. Aṣeyẹ ọjọ na dun ẹ larinrin, irohin ko to afọjuba ni.



# Ayanwale komojade



### Awo pe Asylam ati Iwe Irohin "Pilot" lejo

# Wo o, kio tun wo!



# Musulumi Igede s'ajoyo ojo ibi Anabi






## Taji loju oorun Ki o si s'ara giri!

Pelu

ANDREWS LIVER SALT



ANDREWS

LIVER SALT


# Osugbo Iwase Eko se eye fun awon iko lati eka Londonu



# Ogundeji f'arugbo ara wo ewon


OVALTINE

Ntun agbara ati okun-inu se



# Oloye Awolọwọ lọ ṣe ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ipinlẹ mẹtẹta

IBADAN.

OLOYE Ọbafẹmi Awolọwọ, Olori Apapọ gbogbo Ẹgbẹ Afẹnifẹre ati Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Apapọ Ijọba Naijiria pẹlu awọn Igbimọ Iriju Ẹgbẹ Afẹnifẹre dide irin-ajo ọjọ mẹrindiladọta ni ọjọ Ọjọbọ ti iṣe ọjọ kẹtadilọgbọn oṣu ti o kọja yi lati lọ ṣe ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni Ipinlẹ Ariwa, Ipinlẹ Ila-Orun ati ni Arin Agbedemeji Aala Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria.

Nigbati nwọn dide irin-ajo lati Ibadan ni ọjọ na, Ipinlẹ Ariwa ni nwọn kọkọ lọ nibiti Oloye Awolọwọ gbe ba ipade Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre ilu na sọrọ. Awọn Aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre ti o ba Olori Apapọ Ẹgbẹ na lọ ni awọn wọnyi: Dokita E. A. Awoduche Aṣiwaju Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ Ila-Orun, Oloye Ayọ Rosiji, Akọwe-Agba Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre; Oloye S. O. Ianlẹhin; Oloye F. R. A. Williams, Onimọran Ẹgbẹ Afẹnifẹre nipa ofin; Ọgbẹni O. Agunbiade Bamiṣe, Oga-Alamojuto Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Awọn yoku ni:—Ọgbẹni S. O. Ikoku, Obakeji Akowe Akapo Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Oloye Tony Enahoro, Aṣiwaju Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Ọgbẹni O. Dosunmu Akọwe Alamojuto ohun-ini Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Ọgbẹni J. S. Tarka, Olori Ẹgbẹ UMBC dapọ mọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre (AG/UMBC) ati ọkan ninu awọn aṣiwaju Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre Alhaji Ibrahim Imam, Aṣiwaju Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ati ọkan ninu awọn aṣiwaju Apapọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre, Ọgbẹni A. Rewane, Akọwe Iṣẹ-iṣelu fun Oloye Awolọwọ ati Ọgbẹni S. T. Ọrẹdẹin, Akọwe-Agba Eto Ẹgbẹ Afẹnifẹre.

Nigbati nwọn de Ipinlẹ Ariwa, Oloye Awolọwọ ati gbogbo awọn ẹmẹwa rẹ na ṣe ibẹwo ilu Jos, Makurdi ati Kafanchan, nwọn si ti ibẹ rekọja lọ si Enugu lẹba Oboko ati Oturkpo ni ọjọ karun oṣu yi. Nigbati nwọn wa ni Enugu, nwọn lọ si ipade Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ na, nwọn si ba gbogbo enia sọrọ ninu ipade na. Oloye Awolọwọ yio si ba ọkọ-ofurufu da kan-an wa si Ibadan ni ọjọ kẹwa oṣu yi.

Ni ọjọ kini oṣu kejila ọdun yi ni Oloye Awolọwọ yio de ilu Kalaba pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ lati ba awọn Ẹgbẹ ilu Etido Kalaba, Ogoja ati Rivers sọrọ ninu ipade Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ipinlẹ na, yio si tun ba ajọ Igbimọ Iriju Ẹgbẹ na sọrọ ninu ipade wọn. Lati ilu Kalaba ni nwọn yio ti lọ si Onitsha ni ọjọ keje oṣu na, nwọn yio si de ilu Asaba ni ọjọ keji lati ba ipade gbogbogboo ẹgbẹ na sọrọ nibẹ.

Nigbati nwọn ba kuro ni ilu Asaba ti nwọn ba nlọ siIu Ibinni, nwọn o ya lọna ba wọn ṣe'pade gbogbogboo Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ilu Bojiboji, Agbor ati Abudu, nwọn yio si sun ni Ibinni. Ni ọjọ kẹsan oṣu na, nwọn yio lọ si ipade gbogbogboo Ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre Aarin Agbedemeji Aala Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni Ibinni nwọn yio duro nibẹ titi di ọjọ kọkanla oṣu na, Nwọn o si ti ibẹ pada wa si Ibadan ni ọjọ kejila oṣu kejila ọdun yi.



OLOYE OBAFẸMI AWOLỌWỌ
Olori Ẹgbẹ Afẹnifẹre

## AKIYESI FUN ONKAWE

**Eyi ni lati sọ fun nyin pe, ẹnikẹni ninu ẹnyin onkawe ti o nkọwe si Olotu Iwe Irohin Yoruba ti ko ba fẹ ki iwe on sọnu ki o maa kọ ọ taara si ile iṣẹ rẹ ni:**

**Allied Newspapers Limited,
Elephant House
214. Broad Street, Lagos**

## Itan Ti Julius Sọ Lori Ọti Waini Ti O Nfunni Ni Ilera



*Ẹ Ka nkan ti ọti Atẹjẹṣẹ* PHOSFERINE TONIC WINE *ṣe fun Julius Ajayi ti ongbe, 3, Akintoye Street, Yaba, Lagos.*



**Lọ Si Sọbu Ibiti O Ti Nra Ọja Kiakia ki O Si Ra Ọti Waini Atẹjẹṣẹ, PHOSFERINE TONIC WINE Fun Ara Rẹ**

*Maṣe gbagbe lati yi ẹrọ asọrọ magbesi rẹ (Radio) si si ibiti O ti le gbọ "Famous Fortunes", awọn itan ti wọn sọ bi a ti le ri iyege ninu gbogbo nkan ti aba nṣe.*

*Kọwe si Phosferine Tonic Wine, P.O. Box 497, Lagos fun iwe kekere ti O sọ bi O si le ni ilọsiwaju.*

# Ori lo mọṣẹ aṣela ẹni (4)

OLOTU, karaole o! Mo ro wipe gbogbo nyin ni yio ti ranti wipe, ibiti a ti ba ọrọ wa na de ni ibiti Alfa na gbe pari ọrọ rẹ si wipe:—"Eyi ti mo ri ni mo sọ fun ọ yi o, ṣugbọn o ku si ọwọ ara rẹ nisisiyi lati yanju ọrọ ara rẹ". Bayi ni Alfa na bą gbe ọpọn yanrin rẹ kuro nilẹ, o si palẹ gbogbo rẹ mọ wole.

Eyi je iyalẹnu nla fun ọmọ yi lati ri i wipe iru ọrọ yi ni on ba pada lọdọ Alfa nla yi, ọrọ na si pesijẹ patapata to bẹ ẹ ti ọmọde yi ko fi dagbere fun Alfa na wipe on nlọ sile, nṣe ni o ṣa rọra dide nilẹ jẹ ẹ, ti o si bọ sode, bayi ni ọmọ na ṣe wa sile pẹlu ironu, to bẹ ẹ ti ekeji rẹ fi mbere lọwọ rẹ wipe "ha -ha a! Nibo ni ẹ ha ti lọ lati owurọ to bayi? Tabi Ọlọrun ti pese iṣẹ kan fun nyin ni?"

### ỌRỌ PESIJẸ

Ọrọ pesijẹ fun ọmọde na patapata, ko le fesi kan si ibere ekeji rẹ taara, nṣe ni o ṣa nwo du u. Nigbati ekeji rẹ yin in, yin-in, yin-in, ti ko gbọ esi kan lẹnu rẹ nipa ohun ti o ṣẹlẹ si, ti o fi dakẹ pẹlu ironu, ti ko si ṣe alaye kan, ni o ba fi ọran rẹ ti, o nwo o lasan, nwọn si mba aniyan lọ gẹgẹbi iṣe wọn si ara wọn tẹlẹtẹlẹ.

Ṣugbọn nigbati o nlọ bi ọsẹ kan sẹhin ti ọmọdekunrin yi wa ninu ironu lori bawo ni on yio ti ṣe le yanju gbogbo iṣoro wonyi, o pinnu lọkan ara rẹ ni ọjọ kan lati gbiyanju gẹgẹbi imọran ti Alfa na fun un.

Bi ilẹ ti mọ ni owurọ ọjọ kan, bi ekeji ọmọde yi ti lọ si ibi iṣẹ tan ni on na ba jade nile, o si bẹrẹsi rin kakiri ilu titi di irọlẹ ọjọ na kẹdẹrẹ.

Nigbati o de adugbo nla kan, o ṣe akiyesi wipe adugbo na yatọ pupọ, atipe, on paapa ko de adugbo na ri tẹlẹtẹlẹ lati igbati nwọn ti de ilu na. O bere lọwọ awọn alarekọja pe: "ẹ jọwọ, orukọ wo ni nwọn npe adugbo yi? Ati pe, kiniṣe ti adugbo na fi dara to bayi?"

## ỌRỌ AKEWI

**Lati ọwọ Ọmọ-ọba Akibu Alarape, Ibadan**

### ADUGBO ỌBA

Awọn alarekọja na si sọ fun un pe adugbo Ọba ni ati pe gbogbo ọṣọ oriṣiriṣi ti nwọn nṣe lọwọ lọwọ si gbogbo adugbo kakiri yi jẹ ti eyẹ ipalẹmọ fun ti Ọba na ti yio de ni ọsẹ ti o mbọ lati irin-ajo ti o ti lọ lati nkan bi oṣu mẹta.

Nigbati ọmọde na gbọ



AKIBU ALARAPE

irohin na bayi tan, o tun bẹrẹsi yipo kakiri adugbo na gẹgẹbi iṣe rẹ, o si nworan oniruru ọṣọ ti nwọn ta yipo adugbo na fun aṣeyẹ abọ Ọba na. Nigbati o tun rin kọja lọ siwaju diẹ, ni o ba ja sinu agbala nla kan. Agbala na jẹ eyiti o le ba ẹnikẹni lẹru nitoripe ibẹ gan an ni Afin Ọba.

Irohin ko to amojuba ni ẹwa oniruru aṣọ ti nwọn fi ṣe ọṣọ si ibugbe Ọba na Lẹsẹkẹsẹ ni ọmọde na ti ro ninu ọkan ara rẹ pe boya on yio ri iṣẹ diẹ ṣe nibẹ nitoripe, o fẹrẹ jẹwipe gbogbo agbo-ile na ni o kun fun oniruru dukia iyebiye.

Kẹrẹkẹrẹ bẹ ẹ ni ọmọde yi fi bọ sinu agba Ọba. Ṣugbọn ki o to di akoko yi, ilẹ ti bẹrẹsi ṣu diẹdiẹ to bẹ ẹ ti ọkan ọmọde yi ko fi balẹ mọ rara, o si bẹrẹsi wa oju ọna lati jade.

### ẸRU BA A

Bi o ti nwa ọna lati jade nitoripe ọkan rẹ ko balẹ mọ, ẹru si mba a gidigidi, inu agbala nla miran ni o tun jasi, ibẹru pẹlu jinni-jinni ọkan si mu u to bẹ ẹ ti ko fi mọ ohun ti yio ṣe mọ nitoripe ilẹ ti tubọ nṣu, okunkun si kun ṣugbọn imọlẹ ina Ọba ti nwọn tan yika inu agbala na ni ko jẹki ẹru tubọ ba a ju bẹ ẹ lọ, awọn ọlọpa si ti bẹrẹsi tilẹkun agbala afin Ọba na ni ọwọ-inu gẹgẹbi iṣe wọn.

(Wo oju ewe kẹwa)




DA

INU-RIRUN DURO

Nigbati o ba ni irora ninu ikun rẹ, ohun ti o nfa idi rẹ nigbagbogbo ni pe omiro ti pọju nibẹ. Omiro yi ni o nfa arun-inu, inu-kikan-ni ati airi-igbẹ-ya.

Ṣa ti mu ẹgbogi Phillip's 'Milk of Magnesia' diẹ .........yio si ko rirogun omiro na kuro, a si le irora na lọ werewere. Yio fun okun-inu lagbara lati ti gbogbo nkan ti o nfa irora na jade kuro lara.

Ko lewu, o rọrun lati lo, o si tu ni lara.

'MILK OF MAGNESIA'

Awọn ti o nṣe e ni

PHILLIPS



ODARA FUN GBOGBO ẸBI



PALM LINE

wa fun iṣẹ rẹ



Fun kiko oriṣiriṣe ọja wọlu ti enia ni lati ma a lo lojojumọ lọ si idi irinṣẹ ohun ọgbin ati ti ẹrọ, awọn ọkọ Palm Line titun ni o yaaju fun iru iṣẹ bẹẹ nipa titete ṣẹẹ ati ṣiṣe dada nigbakugba. Ẹrukẹru ti o ba ti ni fifi ọkọ ko Palm Line ni gbogbo irinṣẹ ti o yẹ fun un,—o si wa fun iṣẹ rẹ nigbakugba.





Iṣẹ wa ni lati ma a ko gbogbo ẹru nyin

Koowa fun PALM LINE

## Tarpaulin Industries (W. A.) Ltd.

**Ni awọn onisowo igbokun (TARPAULIN) Naijiria, ti nwọn ndabo Koko ati Ekurọ, itẹsilẹ fun Koko ati Ekurọ, ti nwọn ndabo mọto-akẹru ati awọn aṣọ Igbokun miran.**

P. M. B. 2227
1 DOCKYARD ROAD, APAPA.

Telegrams
TARPIND Lagos



**DA ẸHIN-DIDUN RẸ DURO**

nipa titete mojuto awọn eree inu ati apo-itọ rẹ

LO

**DeWitt's**
**Kidney & Bladder Pills**

Ki o si bọ lọwọ awọn irora ti o nkọ ẹ sinu arun

**LAKUREGBE, ARA-RIRO, ẸHIN-DIDUN ati, Awọn IYỌNU APO-ITỌ**




**DeWitt's**
**Kidney & Bladder Pills**

L'arin wakati diẹ ni wa a ti Ri ayipada lọ rẹ (Ilọ a mu awọ miran wa)


# Adọfa Ọmọ-Ẹgbẹ Alakukọ wọ Ẹgbẹ Ọlọpẹ ni Iwo

IWO.

LAIPẸYI ni Ọgbẹni Oseni Arẹmu ti ise olori Ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) ni ilu Iwo ko gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ re wa si Ipade Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group), nwọn si wọ ẹgbẹ na. Gbogbo awọn ti o gba iwe iwọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre na jẹ mejidiniadọfa (108), gbogbo wọn si pinnu wipe awọn di ọmọ Ẹgbẹ Afẹnifẹre lati ọjọ na lọ, nwọn ni awọn ko se Ẹgbẹ Alakukọ mọ.

Ọgbẹni Oseni Arẹmu, olori wọn si se alaye ninu ipade na pe gbogbo ọrọ ẹtan ti awọn ti dimu lati da owo ribiribi sinu Ẹgbẹ Alakukọ jẹ ipalara fun awọn, wahala ati iyọnu ati ijongbọn ni awọn fi owo na ra fun ara awọn.

Ninu awọn ọrọ ẹtan ti awọn Ẹgbẹ Alakukọ sọ ni igba idibo ni wipe awọn yio pa owo-ori rẹ. O wa han si awọn gbangba wipe ọrọ ẹtan ni gbogbo ileri Ẹgbẹ Alakukọ, nwọn ni awọn si ti yọ'wọ yọ'sẹ ninu ẹgbẹ na.

*Ẹ ma a ka Iwe IROHIN YORUBA nigbagbogbo fun irohin aladun*

## Akiyesi fun awọn onkawe

**Eyi ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin ti ẹ kọwe bere Iwe Irohin Yoruba ti 28:9:60 ati ti 5:10:60 pe ki ẹ mu suru fun wa diẹ nitori eyiti o sẹku, nwọn ti tun ra wọn tan. Sugbọn a ti se ikede fun gbogbo awọn aṣoju wa kakiri ilu pe eyiti nwọn ba ta sẹku ki nwọn da wọn pada fun wa ki a le pin in fun nyin.**

**Olotu.**


# THE NATIONAL BANK OF NIGERIA LIMITED

## BALANCE SHEET AS AT 30TH JUNE, 1960.

**LIABILITIES**

| | | |
|---|---|---|
| AUTHORISED CAPITAL:— | | |
| 1,000,000 4% Cumulative Non-Participating Preference Shares of £1 each | £1,000,000 | |
| 250,000 Ordinary Shares of £1 each | £ 250,000 | |
| | £1,250,000 | |
| SHARE CAPITAL ISSUED AND FULLY PAID:— | | |
| 1,000,000 4% Cumulative Non-Participating Preference Shares of £1 each | £1,000,000 | |
| 168,978 Ordinary Shares of £1 each | 168,978 | £1,168,978 |
| RESERVE FUNDS | 170,000 | |
| PROFIT AND LOSS ACCOUNT:— | | |
| Balance Carried Forward | 1,416 | 171,416 |
| Current Deposit and other Accounts including Reserve for Contingencies | | 10,132,960 |
| Liabilities of Customers for Acceptances, Endorsements, Engagements, etc., as per Contra | | 1,403,443 |
| | | £12,876,797 |

AKINOLA MAJA, Chairman
T. A. DOHERTY, Managing Director
S. O. GBADAMOSI, Director
J. K. LADIPO, Director

**ASSETS**

| | | |
|---|---|---|
| Cash in hand and at Bankers | | £1,748,976 |
| Money at Call and Short Notices | | 1,250,000 |
| British and Nigerian Government Treasury Bills | | 349,423 |
| INVESTMENTS AT OR UNDER MARKET VALUE:— | | |
| British Government Securities | £178,990 | |
| Nigerian Government Securities | 126,220 | |
| Other Securities | 231,122 | 536,332 |
| Loans, Advances to Customers and other Accounts Less Provision For Bad and Doubtful Debts | | £7,016,762 |
| Furniture, Stationery Stock and other Accounts Less Depreciation | | 68,763 |
| Premises Account At Cost, Less Depreciation | | 503,098 |
| Liabilities of Customers for Acceptances, Endorsements, Engagements, etc., as per Contra | | 1,403,443 |
| | | £12,876,797 |

S. T. HUNPONU-WUSU, Director
A. A. O. DUROSHOLA, General Manager
E. O. OBASA-PORTER, Chief Accountant

### AUDITORS' REPORT

We have obtained all the informations and explanations which to the best of our knowledge and belief are necessary for the purpose of our audit. In our opinion, proper books of account have been kept by the Bank so far as appear from our examination of those books, and proper returns adequate for the purposes of our audit have been received from the Branches. We have examined the above Balance Sheet which is in agreement with the books of accounts and returns of the Bank. In our opinion and to the best of our information and according to the explanations given us the said Balance Sheet is properly drawn up so as to exhibit a true and correct view of the state of the affairs of the Bank at the 30th June, 1960.

Dated at Lagos this 29th day of September, 1960.

THOMAS, SILVA, DAWODU & CO.—Auditors
Certified Accountants

## PROFIT AND LOSS ACCOUNT FOR THE YEAR ENDED 30TH JUNE, 1960

| | | | |
|---|---|---|---|
| Provisions For Dividends | £ 65,347 | Profit after Providing for taxation and after making transfers to Credit of Inner Reserves | £ 85,742 |
| Reserve Funds | 20,000 | Balance Unappropriated at 30th June 1959 | 1,021 |
| Balance To Be Carried Forward To Next Year | 1,416 | | |
| | £ 86,763 | | £ 86,763 |

AKINOLA MAJA, Chairman
T. A. DOHERTY, Managing Director
S. O. GBADAMOSI, Director
J. K. LADIPO, Director

S. T. HUNPONU-WUSU, Director
A. A. O. DUROSHOLA, General Manager
E. O. OBASA-PORTER, Chief Accountant


Published by Allied newspapers Limited, Elephant House 214, Broad Street, Lagos and printed for them by Amalgamated